# IFARARUBỌ HANNA

**(Ẹkọ Fun Ọjọ Awọn Iya)**
**1 Samuẹli 1:1-28**
**ẸKỌ 71 FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI:"Bọ̀wọ fun baba ati iya rẹ; eyi ti iṣe ofin ikini pẹlu ileri" (Efesu 6:2).**

### Nigbakuugba Yoo Ṣẹ́ Ku Diẹ Silẹ

Ni akoko awọn onidajọ, ki Israẹli to ni ọba, tọkọ-taya kan wà ti wọn jẹ olufọkansin eniyan, orukọ wọn a maa jẹ Hanna ati Ẹlkana. Lati fi ifẹ wọn si Ọlọrun hàn, wọn a maa lọ si Agọ ni ọdọọdun lati jọsin ati lati ni ipin ninu awọn ase àjọ. Ni akoko yii ipo ti Israẹli wà nipa ti ẹmi jẹ eyi ti o buru pupọ, ṣugbọn ohun afiyesi ni pe Ọlọrun a maa ni awọn diẹ ti o jẹ oloootọ ti yoo maa sin In paapaa ni akoko ti ijọ tilẹ n la igba okunkun biribiri kọja.

Hanna n fẹ ọmọkunrin kan, ṣugbọn ọdun n gori ọdun, sibẹ oun ko ni ọmọ ti yoo maa tọju ti yoo si maa kẹ́. Eyi mu inu rẹ̀ bajẹ lọpọlọpọ. A kà a si ọla pataki lati bi ọmọkunrin.

### Ẹ̀jẹ́ Hanna

Bi akoko ti n kọja lọ ibanujẹ rẹ tubọ n pọ si i; ni ọjọ kan nigba ti o wà ni àjọ kan ni Ṣilo, o sọ ibanujẹ rẹ fun Ọlọrun. Inu rẹ bajẹ to bẹẹ ti ko le jẹun. O mọ pe Ọlọrun fẹran oun ati pe yoo si ran oun lọwọ, nigba ti ẹnikẹni kò le mu inu rẹ dun. Kò tilẹ kigbe soke nigba ti o n gbadura si Oluwa, nitori Oluwa le ri adura ọkàn rẹ̀. Nigba miiran awa paapaa a maa gbadura tọkantọkan to bẹẹ ti a ki i ri ọrọ lati fi sọ ohun ti ọkàn wa n beere. Ṣugbọn Ọlọrun ri adura ati ifararubọ ti a n ṣe pẹlu "irora ti a kò le fi ẹnu sọ." Ẹmi Ọlọrun a maa ràn wa lọwọ ninu adura bẹẹ; a si maa n ri esi gbà.

Bi Hanna ti n gbadura, o sọ fun Ọlọrun bi inu oun ti bajẹ to, nitori oun ko bimọ. O ṣeleri pe bi Ọlọrun ba le fun oun ni ọmọkunrin kan, oun yoo fi fun Oluwa ni gbogbo ọjọ ayé rẹ̀, ati pe abẹ ki yoo kan an ni ori. Kikun irun jẹ apakan ẹ̀jẹ́ awọn Nasiri, ti wọn n ya ara wọn sọtọ fun iṣẹ pataki fun Ọlọrun. Ẹ̀jẹ́ yii le jẹ fun ọsẹ kan, oṣu kan, tabi jalẹ gbogbo ọjọ ayé ẹni naa.

Nigba ti Eli, olori alufaa, ri ti ete Hanna n mì ṣugbọn ti ko gbọ́ ọrọ kan, o rò pe boya o muti yó ni. O wi fun un pe ibanujẹ oun ni o mu ki oun gbadura tẹduntẹdun to bẹẹ ti o fi jẹ pe ẹnu rẹ ni o n mi ṣugbọn kò sọ fun un ohun ti oun n beere. Eli ri i pe oun ti sọrọ ti ko tọ́ si i, o si yara lati tù u ninu. O gbadura pe ki Ọlọrun dahun adura rẹ ki o si fi ọpọlọpọ ibukun fun un.

### Alabukún-fun nipa Igbagbọ́

Hanna ni igbagbọ́ pe Ọlọrun ti gbọ́ adura oun ati pe Yoo si fun oun ni ohun ti oun n beere. O ni idaniloju ti o duro ṣinṣin ninu ọkàn rẹ bi ẹni pe o ti ni ọmọ naa, nitori Iwe Mimọ sọ pe o jẹun, "kò si fà oju ro mọ." Igbagbọ́ rẹ̀ ti mu ki o layọ.

### Akoko fun Isin

Ni owurọ ọjọ keji nigba ti Hanna ati ọkọ rẹ mura tan lati pada si ile, wọn kọkọ sin Ọlọrun. A ko gbọdọ maa kanju nitori iṣẹ wa to bẹẹ ti a ki yoo fi ri àye lati dupẹ lọwọ Ọlọrun fun awọn ibukun Rẹ̀ ki a si beere fun itọsọna Rẹ̀ ni gbogbo ọjọ naa, a si ni lati ka Ọrọ Rẹ̀ ki a ba le mọ̀ ohun ti O n fẹ ki a ṣe. Boya Oun ni ibukun pataki tabi ileri pataki kan fun wa ni ọjọ kan, a o si padanu gbogbo nnkan wọnyii nipa ṣiṣe alaibikita lati ka Bibeli. Lati mọ ifẹ Ọlọrun ṣe pataki fun wa ju ohunkohun ninu ayé wa lọ. Bi a ba ṣe alainaani Ọrọ Ọlọrun, a o sọ asà ti a le fi kọjuja si ọ̀tá ẹmi wa nù.

### Hanna Ranti

Hanna ti ṣe ifararubọ rẹ si Ọlọrun, o si ti gbagbọ pe yoo gbọ adura oun; nigba ti akoko to a bi Samuẹli lati san èrè igbagbọ rẹ fun un. Oun kò gbagbe ẹ̀jẹ́ ti o ti jẹ́ lati fi i fun Oluwa lati maa sin ninu Tẹmpili ni gbogbo ọjọ aye rẹ̀. O fẹran ọmọ rẹ̀ pupọ, ohun ti o rọrun fun un ni lati wi pe, Ọlọrun ti fi ọmọ naa fun un lati mu inu oun dùn, ati pe Ọlọrun ki yoo beere pe ki oun mu un lọ si ile Ọlọrun lati maa wà nibẹ nigba gbogbo. O ranti ileri rẹ ti o ṣe fun Oluwa; nigba ti Samuẹli dagba to lati fi iya rẹ̀ silẹ, o mu un lọ si ọdọ Eli, olori alufaa, lati maa ṣe iṣẹ ti o le ṣe. Samuẹli jẹ ọrẹ ọ̀wọ́n si Oluwa.

### Ere Ifararubọ

Ọlọrun yẹ́ ifararubọ Hanna sí O si fun un ni ọmọkunrin mẹta si i, ati ọmọbinrin meji lati fi inu didun kun ile wọn. Ọlọrun a maa san ere fun ifararubọ ti awọn ọmọ Rẹ̀ ba ṣe, O si ti ṣeleri ọpọlọpọ fun awọn ti o ba kọkọ wá Ijọba Ọlọrun ati ododo Rẹ̀.

Hanna kò gbagbe iṣẹ rẹ gẹgẹ bi iya si Samuẹli, ṣugbọn a maa lọ lọdọọdun si Ṣilo pẹlu ẹwu kekere kan ti o dá fun un.

**Ọmọ Kekere yoo si maa Tọ́ Wọn**

Samuẹli fi ọkàn otitọ sìn ninu Ile Ọlọrun lati igba ti o wà ni ọmọde. Awọn miiran gbagbọ pe awọn ọmọde ni lati dagba na ki a to bẹrẹ si i kọ wọn ni ohunkohun nipa ẹsìn. Wọn ro pe awọn ọmọde kò le mọ nipa ohun ti i ṣe ti Ọlọrun. Ṣugbọn ọkàn rirọ̀ ati ti otitọ ti o wà ninu ọmọde a maa tete yara gba Ọrọ otitọ ati mimọ́ ju ọkàn awọn agba ti ẹ̀ṣẹ ti sọ di ibajẹ ti o si tun kún fun ariwisi. A ri ọpọlọpọ awọn ọmọde ti wọn ti fẹran Jesu lati igba ti wọn ṣẹṣẹ bẹrẹ si i sọrọ, awọn ẹlomiran a si ri igbala nigba ti wọn ṣi wa ni ọmọ ọdun mẹrin tabi marun-un. Nipa fifi ọkàn wọn fun Jesu nigba ti wọn wà ni ọmọ kekere, wọn ko ni ni ipin ninu wahala ati ibanujẹ ti ẹ̀ṣẹ maa n kó bá eniyan.

**Eniyan Nla Ọlọrun**

A ka a pe Samuẹli dagba o si di eniyan nla fun Ọlọrun. Yatọ si jijẹ alufaa ninu Agọ, oun ni onidajọ ikẹyin ti o ṣe akoso ijọba Israẹli. Wo o bi inu Hanna yoo ti dun to lati ri i pe ọmọ oun de iru ipo giga bẹẹ nipa ti ẹmi ati ninu ọran iṣelu! Bayii ni a san ẹsan ifararubọ rẹ̀ si Ọlọrun pada fun un nipa igbesi-ayé ẹni iwa-bi-Ọlọrun ti ọmọ rẹ̀ akọbi gbé.

**AWỌN IBEERE**

1. Nibo ni Hanna ati Ẹlkana maa n lọ ni ọdọọdun? Ki ni ṣe?
2. Ki ni ṣe ti inu Hanna bajẹ?
3. Ta ni Hanna sọ ibanujẹ rẹ̀ fún?
4. Ki ni Eli ṣe nigba ti o mọ̀ nipa ibanujẹ rẹ̀?
5. Hanna ha gba Ọlọrun gbọ́ lẹsẹkẹsẹ? Bawo ni a ṣe mọ bẹẹ?
6. Ki ni Hanna ṣeleri lati ṣe bi a ba fun un ni ọmọkunrin kan?
7. Njẹ o ṣe gẹgẹ bi ileri rẹ̀ bi?
8. Ki ni ere ti o ri gbà?